# IROHIN IMỌLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

NO. 876 SATURDAY DECEMBER 19, 1964 (2D)


## Awọn Osisẹ Binu Da Isẹ Silẹ

KASABLANKA:- Ni deede agogo mẹsan owurọ ana ọjọ Ẹti tiṣe ọjọ kejidinlogun osu yi, ni irohin de si eti gbọ wa wipe gbogbo awọn osisẹ Ijọba ti wọn le ni ọkẹ meje ( 135, 000 ) enia ni gbogbo wọn ti binu da isẹ silẹ ti wọn si kọ lati ṣisẹ.

Gẹgẹbi irohin ti agbọ, iwe Irohin kan fi ye wa wipe awọn oṣiṣẹ na ti nbere fun ẹku wo owo osu lọdọ Ijọba, nigbati Ijọba ko si kọ ibi ara si ọrọ wọn, ni gbogbo wọn ba ṣe binu ti wọn si da isẹ silẹ lana nitori ẹkunwo owo osu.

Agbọrọsọ awọn ẹgbẹ osisẹ ilu Kasablanka fi ye awọn oniwe irohin ninu ipade wọn kan lana wipe ọkẹ kan o le ẹgbẹdọ g b ọ n (135, 000) enia, ni awọn osisẹ ile isẹ miran niwọn o tun lọwọ ninu ida sẹsiiẹ na ni owu rọyi bi Ijọba ba fariga ti nwọn si kọ lati da awọn osisẹ na lohun, ibere wọn.

Agbọ wipe ko si ija igboro ninu ilu n a larin awọn osisẹ, lati igbati wọn ti da i s ẹ silẹ sugbọn gbogbo nkan ni ko lo deede mọ ti awọn enia kosi ri oja ta ra ninu ile ita ja awọn Oyinbo onisowo.

Bi awọn oslsẹ na ba pada si ẹnu isẹ won ati bi nkan ba ti nlo ni ilu na, ẹ o tun ma a gbo ninu iwe Irohin wa.

# AWỌN ỌMỌ ILE-IWE KO TUN GBỌDỌ DA'RUKỌ AWOLOWO MO ?

**ABẸOKUTA:— Gbogbo enia lo b (rési forikor' n' meji mẹta ti nwọn si nsọrọ kẹlẹkẹlẹ kakiri gbogbo adugbo ni ọjọ Ẹti ti iṣe ojo kejidinlogun oṣu yi nigbati gbogbo wọn gbe ile gbọ wipe Ijọba Ibilẹ Afunnisho Ẹgba Ọbafẹmi ti ṣe ofin pe awon omode ko tun gbodo korin tabi kigbe oruko awon Asiwaju ẹgbẹ oṣelu mo.**

N nu ipade kan ti awọn Aiaṣẹ Ijọba Ibilẹ Afunnishọ na ṣe, nwọn paṣẹ wipe ọmọde to ba ti ju ọmọ ọdun mẹrindinlogun lọ ko gbọdọ tun kọrin tabi kigbe Oruko asiwaju ẹgbẹ Oṣelu.

Ọmọ ti ọjọ orirẹ ba ti le ni Ọdun mẹrindinlogun ti o ba kọrin tabi pe orukọ Aṣiwaju ẹgbẹ Oṣelu, Ohuniti o mu ọmo na kigbe, tabi ti o kigbe ki ọmọ na to kigbe, tabi ti o mu ọmọ na kigbe lugbadi Ofin Ijọba

Oluware yio fi Pọn un mẹdọgbọn (£ 2 5) tanran si kotu tabi ki o lọ fi ẹwọn oṣu mẹta jura

Ni afikun Ijọba Ibilẹ na tun ṣe e ni Ofin pe gbogbo enia, tabi ẹnikẹni ko tun gbọdọ jade si ita lati agogo mẹjọ alẹ titi di agogo ma run daji ọjọ keji.



**Oloye Ọbafẹmi Awolowo**

Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

### OFIN IṢEDE

Nitorina g b o g b o awọn enia ti o ngbe Ẹgba Ọbafẹmi ati agbegbe rẹ ko tun gbọdọ jade si ita lẹhin agogo mẹjọ alẹ titi di kutukutu owurọ ọjọ keji bi oluwarẹ ko b a f ẹ fi rakẹfun tabi lugbadi ofin.

Onirohin kan ran wa lati wipe, o f e r e jẹ wipe yika gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni ofin isede wa nisisiyi

Gẹgẹbi alaye ti oni-Irohin wa na ṣe fun wa ni alẹ ana, awọn yi ni orukọ diẹ n i n u awọn ilu ti ofin isẹdalẹ ti wa nisisiyi.

Ogbomọshọ ti iṣe ilu Oloye Samuel Ladoke Akintọla Alakoso Ijọba ipinlẹ Iwọ o r u n Ẹgba Ọbafẹmi, Ẹgba Ọdẹda, Akurẹ, Ado-E k i t i, Ile-Ifẹ ati Oshogbo.

O n i r o h i n wa ni Oshogbo fi ye wa wipe Ati alẹ ati owurọ ni awọn enia ma a nfi awo rẹkọdu ti Ọgbẹni I K Dairo ati awon oṣere rẹ ṣẹṣe ṣe da ara laraya kakiri arin ilu.

" Awọn ẹlomiran a gbe aga ijoko wọn si ode, nwọn a si ma a ṣe faaji pẹlu awo rẹkọdu na. ' Ariwo awọn enia na a ma a pọ tobẹ gẹ ẹ, ti o fi jẹ wipe gbogbo awọn ti nlọ ti nwọn nbọ ni nduro ti awọn enia na

" Bi enia ba si gbọ awo rẹkọdu na' bi oluwarẹ ko ba mọ ijọ, yio si ma a " mi, lẹrin gbẹ bi t,Eko,

" Awọn e ia na a, si ma a kigbe ' Awo Awo !! ' nigbati awọn ba gbe nṣere titi di arin oru ni ọjọ miran

" O tilẹ wa jẹ wipe Awọn enia na ko mọ nkan miran mọ ju orin Awolọwọ lọ.

Bi enia ba lọ si oko Awolọwọ ni awọn enia ndarukọ bi o lọ si arin ọja agaga ariwo Awolọwọ ni nwọn npa.

"Paapajulọ awọn ọmode ko tilẹ tun ni orin mẹji mọ ju li Awolowọ yi lọ o wa dabi ẹniwipe ko tun si nkan miran ni Ipinlẹ Iwọ Orun mọ a fi Awo.

Nitori eyi ni awọn enia na ba ronu wipe bi gbogbo nkan ti ṣe nlo yi ti awọn ko ba wa nkan ṣe si ọrọ yi ṣe ẹgbẹ Afẹnifẹre ni yio mokeninu lbo ti mbo yi

Ni awọn enia ba fi nṣe oflo ti nwọn nṣe wọnyi ki ariwo Awo o le ba dinku die larin ilu."

Ṣugbọn On'rohin wa lọ bere Alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Afunshọ Ẹgba Ọbafẹmi ni ana lati gbọ ohunti o fẹ sọ

Bi o ba s t ri alaga Igbimọ na, ẹ o ma gbọ ohunti o ba wi nipa Ofin titun yi.

---

### OGBOMỌSHỌ

Ni ojo Bo tl ise ojo kẹtadinlogun oṣu yi ni awon olopa tun lo mu awon Aṣoju ẹgbe UPGA meji Dokita Christopher Adeoye ati ogbẹni Moses Akande.

Irohln fi ye wa wipe awon enia mejeji na yi ni awon omo Ogbomsho fẹ dibo fun wole ni oruko ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Ogbomsho

Ẹnikẹta ti awon Ọlopa tun mu ni ogbẹni Juseph Oyego ke okan ninu awon gbejoro pataki ni ilu Ogbomosho

Gbogbo awon enia yi nl ôlọpa ko gba iduro wọn nwọn si ko lati fi wọn ṣilẹ

Onirohin wa ni ilu Ogbomoshọ fi ye wa wipe ẹsun ti ọlọpa fi awọn enia na tun niwaju adaju ni wipe awọn enia na to si gbangba ode nwon si nkigbe ẹgbẹ oṣelu kan eyiti o mu ibinu awon ọmọ ẹgbẹ keji wa

Adajo pasẹ wipe ki nwon lo fi awon enia na pawo si ogbaẹwon Ilesha di Otun la

---

## IPADE UPGA

Awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA yio ṣe ipade lo ini deede agogo marun irọlẹ ni opopo Balogun.

Awọn ti o wa ni Ebute Mẹtta yio ṣe ipade ti wọn ni Idi-Araba ni agogo ma run kanna.

Nwọn npe gbogbo ọmọ ẹgbẹ lọkunrin ati l'obinrin.

Tete ra Irohin Imọlẹ tirẹ lọla ki o bale mọ ibiti wọn ma ti ṣe ipade ti ọla.

# IMỌRAN FUN AWỌN ỌMỌ'BINRIN ATI OKUNRIN

(LATI ỌWỌ Anti Afusat)

Jowo Anti Afusat mo fẹ k i ẹ ba ọrọ mi ye mi ọrọ na lọ bayi ọmọ ọdun mẹjidinlogun ni mo jẹ mo si nlọ si ilẹ ẹkọ giga kan ni Ilu Ibadan ti o jẹ ti awọn obinrin ẹlẹgbẹ mi ṣugbọn ti'nba ti wa si ile Ilsiko isimi Iya mi ko gba mi ni aye lati lo ki ọmọ kunrin to jẹ pe mi gangan ni on ni lati fẹ gẹgẹbi ọko mi ọmọ kunrin na fifaran mi pupọ oyi to fi jẹ pe ko le lo ojọ mẹta ki o ma kọ iwe si mi ni ilẹ ẹkọ wa ṣugbọn ọmọ kunrin na nfẹ ri mi ati pe iya mi ko fẹ ri ọmọ na rara kini mo le ṣe bayi Anti Afusati?

CAROLINE
IBADAN

CAROZINE ohun ti mo le fun ọ ni imoran bayi ni ki o ṣe alaye fun Olufẹ rẹ titun na lati ṣe isuru ati pe ki o sẹ alaye fun lori iwa ti iya rẹ nhu ki o si gbinyan lati le wa ọna ti yio fi lọ ri olufẹ rẹ eyi to jẹ pe yio fi wa iya rẹ lori nitori mi ko gbodọ sọ fun ọ pe kl o ko ọrọ si ẹnu Iya rẹ tabi ki o sọ fun olufẹ rẹ na lati wa pade rẹ idi odo tabi ti o ba fe lọ si ọja lati ba sọ nkan to jẹ sọ fun o tabi chun to fẹ fun nyin.

Jọwọ Anti Afusat kini mo le ṣe ti mo le fi jagunmolu lori ifẹ ti mo ni si omidan obinrin kan eyi to jẹ pe iwe kanna lasi jijọ ka eyi to jẹ pe iwe meji ni emi ka bọ si ni on ne, ṣugbọn o fẹran mi pupọ ti fi jẹ pe to ba ti ri mi nse ni iru rẹ na odun sugbọn lọjọ to mọ kọ iwe si omidan na pe mọ fẹ ki a jijo fẹ ara wa ati pe ru ile kanna ni a jijọ ngbe ṣugbọn mi ko mọ ọna ti a le fi ṣe ara wa nigb ti ọmọ na ko gba rara.

Eko Olu

Olu gbogbo ọrọ rẹ yi si bi suiv ati re ọrọ nako iile padọ ti o ba le ni ọ kan suru ati pe ọmọ binrin na ylo jẹ tirẹ ki ise pe iwọ ko wa ọmọ na, ṣugbọn gẹgẹbi iwa rẹ tirẹ lọ nwo ati pe iru ọmọ ti ojẹ lo si nse akiyesi rẹ bayi ma ṣe Iyemeji ọmọ na yio fẹ n ta ba ti nl isuru wipe ọrọ iwe ti jẹ pe iwe kanna ni ẹ jijọ ka eleyi ko di nyin lọwọ lati ma fẹ ara nyin.

Kọ iwe tirẹ ranse si Anti Afusat loni lati gbọ imọran ti yio fun ọ ki o ẹkọ iwe na ki o le teto ọb ọimọran re lori ifẹ rẹ si mọ kunrin ati ọmọ binrin Eyi ni bi o ṣe kọ iwe tirẹ si Anti Afusat, Irohin Imọlẹ 16 Bangbose Street. Lagos

Ma ṣe gbagbe lati kọ imoran ti o fe lati ọdọ mobinrin yi to ṣeṣe de si ile Naijiria lati ile Saro Isierria Leone) yio si ọ ni alaye ti o pe eyi ti o fun ẹ ni ir fiwa ti iwọ yio si lo pe olu- ẹ rẹ titun tabi lori imoran miran lori bi eto igbesi aye ọmọ enia le ṣe dara o dj gt dc.

# YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Ọrọ awọn ọmọ rẹ tabi ti ẹbi le jẹ nkan ibanujẹ fun ọ loni, sugbọn idunnu yio wa fun ọ ni asalẹ.

PICES (Feb 21 - Mar 20) Ọjọ oni dara fuu ọ lati naju lọ, iwọ pẹlu obinrin kan yio pade ara yin, ko si ni jẹki olọ aya fi ki o ba lo pọ.

ARIES (Mar 21 – April 20) Iwọ yio bẹrẹ si gbadun nigbati ọsan ba pọn, gbogbo ohun to buru yio bẹrẹ si dara, iwọ yio si ma gbayi larin ẹgbẹ, sugbọn ki oma sakiyesi ọna ki o to kọja..

FAURUS (April 21 – May 20) Mase gbẹkẹ le enia, ki wọn ma ba gbẹsan lara rẹ, ki osi nifẹ si olufẹ re bi astri ba tu ija yio pari.

GEMINI (May 21 – June 21) Ni ọjọ arẹ rẹ, ati nigba fạji rẹ, nkan iyanu wa nibẹ mas fi ẹnu sere, nitoripe gbajumọ se nkan ọ.

CANCER (June 22 - July 22) Iwọ yio ri iranlọwọ gba lati ọdọ awọn mọle eyiti iwọ yio lo lati fi sẹgun isoro gbogbo, ọro ija atijọ kan yio pari.

LEO (July 23 - Aug 22) Ajeji kan yio wa aann wa si ọdọ rẹ bi aye ba wa ki osee fun, ọpọ ija ti owa nilẹ, ni iwọ yio pari rẹ.

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Mase ro aroka iru iranlọwọ ti o nri gba kakiri, beni kio mase jẹ anikan jọpọn, yi akoko isimi rẹ si ọjọ miran sugbon o dara ki o lọ ra nkan fun isimi loni.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Sa gbogbo agbara rẹ ki gbogbo enia wa fun ọ ni alati lẹhin nipa ọrọ ẹbi.

SCORPIO (Oct 24 – Nov 23) Ire pataki kan mbẹ fuuọ loni nipa iwe kikọ, alejo kan ti iwọ koro tẹlẹ yio jẹki fa ji alẹ oni dun pupọ

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Fi otitọ se gbogbo nkan gẹgẹbi otitọ, ohun ti gbogbo enia nse ni ki ose ẹnu yio si yaọ nigbati oba ri akẹhin si rẹ ko ni siagbara fun ọ mọ

CAPRICORN (Dec 22 – Jan 21) Mase fi asiko kan serel rara bi wọn ba pe ọsi ibi aseyẹ mase kọ lati lo ojo on para fun ere tẹlẹ ki osi papa ibinu rẹ


## Gbanjo ! Gbanjo ! !

FUN ỌDUN KERESIMESI

A ni lati fi kede fun awọn onibara wa pe Ọja gbanjo wa bẹrẹ lati oni lọ titi di 30/11/64. Tete ra irt ki o to kasẹ nilẹ

APEJUWE ILE ITA IWE WA

Wọ Bọọsi Mushin, sọka'ẹ ni Atẹwọlara Bus Stop Bere ladipọ Street, ti o ba rin titi Ladipọ, bere ILE IWE ODU - ABỌRẸ. Ti o ba de ibẹ tan, wa be re Nomba 5, Alaba Stree Mushin, ile iṣẹ wa dojukọ "ODUS SURF" a

AWỌN WA

Olu bori Egbogi Ajẹbidan 40s di 30s Iwe Egbogi Ajẹbidan 25s di 22s Iwe Egbogi Awogba Aruu 20s di 17s Iwe Ilana Ifa purin titẹ ati etu şişe 20s di 17 Iwe Afọşẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalmu Ajẹbidan 3/6 di 2s 6d Tura i Isẹgun Ajẹ 10s 6d di 8s Turari Itaja 10s di 6d 8s Turari Ala r ere 10s 6d di 8s Iye owo Turari pangolo niti oke yi Turari ti o wa ninu pakẹti jẹ 2s 6d pere Iwe Itumọ Ala Joseph Alala 5s Iwe Aniyan eto Irun o ti di 2s 6d Akọnni lẹsin pataki Islam 2s 6d Tailor's Measurement book di 1s 6d

Tenants Agreement Forms 10/6d di 5/ Gold Smith Forms
Certificate of Apprenticeship (mẹta) 17/6 di 10/6d

ỌJA TITUN TI A ṢẸṢẸ RI GBA

Abẹla mimọ fun adura tete Idaloju (oriṣiriṣi awọu fuu Turari.
abẹla mimọ fuu itaja (Kowo wọle pẹlu Turari 20/-
„ „ „ Iṣẹgun Aje pẹlu Turari 20/-
Lọfinda tabi Ororo ipara fun itaja, Iṣẹgun Ajẹ ati arisiki 30/- Igo kan

Fi owo ranṣẹ tabi ki o wa ra ni ọdọ:—
J. O. Shoyinka
5.Alaba Street
MUSHIN.



## Ogun Belubelu Tabi Lẹrẹ

ỌNA ỌFUN — ỌNA ỌRUN

Eeşu nlanla ni lati fi abẹ si ọfun lati ge Belubelu o ti w iku pa ọpọlọpọ enia nipa bayi ati kan Ogun Ajẹbidan ti ati fi wo Ogunlọgọ enia san ni ọjọkan na. Ko Si Tun Se Oluwarẹ Mọ Lailai,

Ẹ BERE LỌDỌ

Ọgbẹni Aro - Lambo

43, Koseh Street, Lagos.

A DAYS REMEDY FOR THE CURE OF

TONSILITIES

WITHOUT OPERATION

**Price 12s 6d**

# IWE SI OLOTU

## Eleyi Ko Ba Oju Mu Masha

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyin mọmọ lati kesi Alaga ile igbimọ Ijọba ibilẹ ilu E k o Alhaji A F Masha lati ba a wa enia to gbe adugbo Adams Street ni i l u Eko ba wa bojuto ọ n a na lati ba tunṣe ki o si ba o j u mu ki o si dabi awọn ọna miran ni ilu Eko.

Ọ n a miran to jẹ pe ko fẹ to ọ n a yi lo'si jẹ pe nwọn ti da ọdaj si ṣugbọn a ko mọ nkan to fa ti nwọn ko fi da ọ d a si io u ara wa'na inu a wa olugbe adugbo na yio dun bi Alaga ile igbimọ I j ọ b a ibilẹ na ba le lo i p o re rere lati tete ṣe ọ n a bi nwọn yio ṣe da ọda soju ọ n a ijafara lewu o. Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ajinde ṣ ma ẹ o.

Emi ni
Bọla Amusa
EKO

## Ilaro Ko Ẹgbẹ Dẹmo Silẹ

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi n i aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ lati kesi awọn olori ẹgbẹ Dẹmọ to wa ni i l u

Ilaro ko ṣe ẹgbẹ Dẹmọ ati pe a ko fi igba kan fi ẹgbẹ Afẹnifẹre silẹ lọjọkọjọ awa ọmọ ilu Ilaro wa lẹhin olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Awo-

lọwọ A si tun ki Adele olori ẹgbẹ na Alhaji D. S. Adegbenro pe ki nwọn ma ni iye meji p e boya awa ọmọ ilu Ilaro nṣe ẹ g b ẹ

Dẹmọ, ẹgbẹ Dẹmọ ti ku patapata ni ilu Ilaro. La ni ko idibo to mbọ yi ni s ẹ-mọ daju pe o titọ ni ẹgbẹ Dẹmọ ti k u ni i l u Ilaro ati agbegbe rẹ.



Oloye S. L. Akintọla
Olori ẹgbẹ Dẹmọ

Mo tun rọ awọn ọmọ ilu Ilaro ti nwọn ni Baba tabi ẹgbọn ti nwọn titori owo nṣe ẹgbẹ Dẹmọ tete jawọ kuro ninu ẹgbẹ ti nwọn fi eru ati p e awọn ọdalẹ lọ wa ninu ẹgbẹ na. "Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi

Emi ni,
Adesina Ọlatunji
ILARO

## Eyin Ọmo Ijesha E Ṣe Suru

Olotu inu mi yio bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin Oloyinmọmọ lati kesi awọn ọmọ iyami ni ilu Ilesha lati lọ se suru lori eto ẹni ti nwọn yio mu silẹ lasiko idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria to mbọ yi ati lati le jẹ ki imọ wọn jẹ ọkan ṣoṣo lori ẹni ti nwọn yio dibo fun.



Oloye Fani-Kayọde
Igbakeji Olori ẹgbẹ Dẹmọ

Eleyi yio si dara ti a ba lọ tete mu iwa edeaiyede kuro larin ẹniti a o mu silẹ ni ilu Ilesha gẹgẹbi asoju wa ni ile igbimọ asofin ti apapọ ilẹ Naijiria mo fi ọrọ mi yi kesi awọn ọmọ ilu Ilesha lati ma fi aye silẹ fun ọmọ ẹ bẹ Dẹmọ ti nwọn yio mu silẹ ni ilu Ilesha ati pe ki ẹ ma ṣe jẹ ki awọn ẹgbẹ na ma yọ pe ija si ti bẹ silẹ tabi a ko mọ ẹniti a le mu silẹ odi ọwọ nyin o. Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Abiọdun Ọshọ
ILESHA.

# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



Aworan ẹgbẹ yi fihan gba gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ wa ni ara rẹ ti nyọọ lẹnu nigba gbogbo. Ibẹ ni a n p e ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngba ṣe igbọnṣẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrin ti o si soro pupọ lati ṣe iwosan r ẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni o wa titi nta kakiri ode nisisiyi ana nwọn ma a npolowo nwọn un iwosan rẹ ṣugbọn bọ́ yi fa le i ri mẹwa ninu awọn gun ti o leṣe iwosan arun

# CYCLOVEN

iy daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn gbe lọ si ile iwosan lati lọ ṣe eyiti o ba nyọ jade omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patpaata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọsẹ dede tabilojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pupọ ojojumọ abi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwu ẹran Ṣuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba Jẹdijẹdi orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ sode ninu omuṣu tabi ti o ba nmu ẹjẹ walẹhin igbọnse tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuṣu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ati awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kio si danwọ kuaju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de ba ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo awọn ti ṇ tanigboro Naijiria bere ni :

NIGERIAN MEDICINE STORS
4 Tinubu Square Lagos
WATER-LOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22878 Nigeria, (Ọja Ita faji
ATI NI ṢỌBU
OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

---

# KẸRẸ O!

Kurani Ọgbọn Eṣu ti a ṣe Larubawa ati itumọ ri sinu Yoruba 25/- Postage 1/6d, Iwe Adura pataki de Arisiki ati iṣegun lori ohun gbogbo lati ilẹ M a 1/6 Iwe Atumọ Ala ati Adura Ala ibajẹ i a ti nta ni 4/- o ti din si 2/6d Afọmọ isin Mohammed 1/— lọdọ:—

Tete ra tirẹ
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue, Lagos Nigeria
(Leti Ọja Jankara l'Eko

---

# Kini E Nduro Fun ?

Bi o ba ni asọ fun fifọ ati lilọ bi ( wollen ) asọ oke, Tapẹta Sapẹti ati orisirisi asọ ti o ba n fun fifọ ati lilọ ni iṣẹju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ

JOYCE LAUNDRETTE SERVICE
34, Ojo — Oniyun Street,
Apapa Road Ebute Mẹtta.

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹsẹ kanna. A le wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ọ ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranṣẹ si wa.
Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi iṣẹ wa ti dara to owo pọọku ni a si ngba

Lati Oju Ewe Keji

Mo ro pe iru ọrọ ti mo nsọ bayi si wa larin a w a enia ilẹ Naijiria paapa ju lọ ni ile aiye ti a wa yi, ṣugbọn iru awọn enia to ma nhu iru iwa bayi ko si ninu wọn to jẹ pe igbẹhin wọn ma ndara.

Ọpọlọpọ lo ma nri adanwo orlṣirişi ni ile aiye ti a wa yi eyi to jẹ pe ninu w a hala kan lo si ma wa ti l a ma tun gbọ pe adanwo na omiran tun ṣẹlẹ si ira awọn enia bẹ kini nwọn yio ṣe ? Ṣugbọn awọn ẹlomiran lo si jẹ pe ninu awọn enia to ti sọ di enia rere ti nwọn si di enia nla lo ma fa i r u lidanwo bẹ fun eyi to jẹ pe ọna kọna ni yio fi ma wa iṣubu rẹ.

Iru nkan bayi lo mu ki ọpọlọpọ lọ ronu ku nigbati nwọn ko ba ni ọkan amumọra. Ṣugbọn bẹ sin ni a ri iru awọn akọni bayi to jẹ pe gbọingbọin ani ọkan rẹ yio si duro ti yio si ma wo iru nkan ti Olorun yio ṣe fun on atipe iru awọn enia bayi ko si pọ ni orilẹ ede aiye yi.

Enyin enia mi mo fẹ kẹ ẹ lọ mọ daju pe ti awọn enia kan ba wa ti nwọn sa titori owo ati ipo ki nwọn na hu iwa to jẹ pe awọn ti nwọn ba ndarukọ B a b a tabi iya to bi wọn sa'ye nigbana eyi ti yio jẹ pe yio wa wọn lati yi orukọ Baba tabi Iya to bi wọn pada nigbati o jẹ pe awọu Oba ti bi wọn si ile aiye ti ṣe iba silẹ ti nwọn si ti gbinka eyi to jẹ pe awọn ọmọ wọn ni yio ma ka eso nkan ti nwọn gbin na.

Njẹ iru Iwa eleyi ha dara bi? kini ẹ lero pe a w ọ n ọmọ won yio ma sọ lẹhin wọn? Ohun ti awọn ọmọ to ti gbinka ati iṣubu awọn enia ti nwọn ti ba jẹ ti nwọn ti ba wọn mu ni pe ki nwọn gbe wọn ma ṣẹ epe

Eleyi yio di ohun ti awọn ọmọ iru awọn enia bayi ko le rin ni ilẹ ti wọn ti bi wọn to fi jẹ pe nṣe ni nwọn yio ma sa kakiri iru nkan ti mo sọ yi na yio tun jẹ ati awọn na ki o to di pe nwon di enia ti y o fi ilẹ aiye silẹ nitori pe i u awọn enia ti nwọn ba hu iwa ọdalẹ tabi ki nwọn wa iṣubu ko ba ti ku lasiko ti nwọn ba wa ni iṣoro njẹ ti awọn enia ti nwọn ti ṣe ibi si ba tun nṣe nkan rere njẹ a tun dara ki awọn enia na tun jijọ fi oju kan ara wọn bi?

Enyin enia mi mo ro pe ọrọ mi yi to lati fi kọ ogbon fun awon ti ko mọ iru iwa to tọ ati ati eyi to yẹ fun wọn lati hu ni ile aye wọn tabi fun awọn ọmọ ile ẹko ti ko ti mo iru iwa ti nwon yio hu lẹhin ola ti awọn ba di ẹniti yio da iṣẹ ṣẹ nitori na ọdalẹ yio ba Ilẹ lọ, Eni da eru ni eru yio tọ lọ, o di gba diẹ.

---

EGBOGI AWỌN ARA ILU FARANSE

# TESSYDRE

Fun Ọmọ — Ọwọ Ati Ọmọde Gbogbo

Tessydre jẹ ojulowo egbogi haunhaun ti meji irufẹ bẹ kosi kakiri igboro ilu Nigeria fun itọju ọmọ ọwọ tabi ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu ẸHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aikole sun yala lọsan twe suu awọn iya wọn gbogbo Ọgọrun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ ṣugbọn kosi eyi ta le fi we egbogi Tessd re rara o. Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn aa ilu Saro ati awọn ara ilu Agonyin (CHANA) mọ egbogi yi dajudaju on na ni wọn si nlọ fun awọn ọmọ ti wọn ba ṣẹṣẹ bi titi fi di nkọn bi ọmẹ ọdun wawa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọka ori inu iwọ aiperi osinu fẹkun fẹkun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ ṣiṣu, gburu tabi aikolokun ninu ara sisu, Inu kunkun iro at fẹfẹ ati orişirişi awọn amodi tabi aisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lenu ni ba Ehin HIHU" gbogbo. Tessy dre a ma mu ki ehin ẹnu rẹ ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati san ara wọn pẹlu.

Awọn ọmọ ti wọn nlo egbogi yi ki saba ṣe am rara niwọn igba ti wọn ba ti ngbọṣẹ dede, ti otutu ko si le ri aye lati duro ni igbaya wọn ti wọn jẹun dara dara ti nwọn si nsun gbadun pẹlu

Bere Egbogi Ni Ṣọbu Awọn:—

WATERLOO STORES
8, Palm Church Street, Lagos
ADEDUN CHEMIST
4, Wakeman Street, Yaba

# IDIJE ! IDIJE !

A fi eyi kede fun awọn Onkawe Irohin Imọlẹ ati awọn Ọmọ karọ- o-jire pe a nfẹ

## ITAN L'EDE YORUBA

Eyiti ẹnikẹni ko ti tẹ jade ninu iwe ri tabi ti nwọn ko ti sọ lori ẹrọ Redio ri Ẹnikẹni ti o ba le lori yio gba

**(£5)** PỌNUN MARUN

Akiyesi;- Kọ itan tirẹ ki o han rekete, ti ẹniti ko bi han a o fa ya ni, ki o si mọ dajudaju pe ko ni ipa ninu Idije na, ITAN ẹniti o ba si daraju a o tẹ ade ninu Iwe Irohin Imọlẹ yi a o si fi lọ(£5 Posta Order) ranṣẹ si

Fi Stamp Tọrọ (3d) ranṣẹ fun gbigbe Pọnun marun (£5) ti o ba jẹ pada si ọ. Ki o ge ibiti Idije yi wa, ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stamp tọrọ rẹ si wa. Ẹnikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranṣẹ siwa ti o ba jẹ iwo na a ko ni fi ranṣẹ si.

Orukọ..............................................

Ibugbe.............................................

.......................................................

Fi itan rẹ ranṣẹ si:-

**Olotu Irohin Imọlẹ**

16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.

---

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TONIC

ALE-BI-ALE Egbogi Tọniki Jamanu titun ti gbogbo ara ilu Eko ati Jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ko ba ṣiṣẹ daradara ti Eemi Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo' tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mọ daju pe "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio yi po pada patapata alafia ati gbadun yio de si ọ Iyen bẹ.



Bere egbogi na ni Ṣọbu
NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos, Nigeria.
ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO IA I*

No 876 SATURDAY DECEMBER 19, 1964 [2D]


## Ọmo Adelabu So Pe On Yio Tọ Ipa Ẹsẹ Baba On

IBADAN:— Ninu ipade kan ti akobi omo Ologbe Alhaji Adegoke Adelabu Ọgbẹni Aderibigbe Adelabu ba awọn oniwe irohin ṣe ni Ile rẹ ni Oke Oluokun Ibadan ni ọjọ Bọ ti iṣẹ ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni o ti se alaye pe on yio tọ ipa ẹsẹ Baba on lori eto ọrọ oṣelu.

Ọgbẹni Aderibigbe Adelabu ẹni ọdun mejilelogun ti o jẹ ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju [UPGA] ti nwọn yio dibo fun ni iha Gusu Ibadan lasiko idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria to mbọ yi. Ọgbẹni Aderibigbe Adelabu tun bu ẹnu atẹ lu ọna ti nwọn ngba nṣe eto ọrọ oselu ni Ilẹ Naijiria o ni titorina ni on ṣe tete tẹle awọn ẹgbẹ to nfẹ ilọsiwaju awọn enia ilẹ Naijiria.

Ọgbẹni Aderibigbe Adelabu tun ṣe alaye pe ohun ti ilẹ Naijiria nfẹ bayi ni awọn Obinrin ati Ọkunrin to jẹ pe nwọn nfẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria ati awọn to jẹ pe nwọn yio se ọna bi ogo ilẹ Naijiria to ti sonu yio se le pada bo si ilẹ Naijiria laipẹ ojo.

# AWỌN ỌMỌ NAIJIRIA NI GHANA FARAMỌ UPGA

**ACCRA-GHANA:- Irohin ko to afojuba ni ipade gbogbo-gbo ti awọn ọmọ Yoruba to mbẹ nilẹ Ghana ṣe ni adugbo kan ti a npe ni Agbo-Malu (Cow lane) nilu Accra Ghana, ni ọjọ kejila oṣu December, 1964, fun idibo sile Igbimọ Aṣofin apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ti ọjọ kusi dẹdẹ yi.**

Onirohin wa ni Ghana fi ye wa pe lati ọjọ ti on ti de Ghana awọn ọmọ Yoruba ati Ibo ko ṣe ipade papọ ri, eyiti nwọn ṣe kọja lọ yi. ki o to to agogo mẹrin irọlẹ ti nwọn fi asiko ipade na si ni ẹṣẹ t'ọmọde-t'agba, l'ọkunrin ati l'obinrin ti pe ṣinṣan Ẹniti ko le rin ni ayafi bi nwọn ba gbe on debẹ' ọmọ Yoruba wa lati oriṣiriṣi ilu pẹlu onilu kọọkan lati ilu kọọkan.

Onirohin wa to mbẹ nilẹ Ghana fi nye wa wipe, awọn ọmọ Yoruba ti nṣe ipade nilẹ Ghana, o ni, ti ọjọ yi kan mama, nitoripe, bi Agbo-Malu ti tobi to, bi Abẹrẹ ba bọ lọwọ eni a l'ọjọ na Abẹrẹ na koni rye delẹ fun ogun lọgọ enia, nipataki awọn ọmọ ibilẹ ilu Ghana.

Nigbati asiko ipade na to, ati wipe ki ẹṣẹ awọn enia jakan-jakan lati oriṣiriṣi ilu nilẹ Ghana pe tan Alhaji Modupẹ-ọrẹ, to wa lati Sẹkọndi dide, o fi Adura ki kun ṣi ipade na.

Lehin adura, Ọlọla Durojayie Thompson, ti iṣe Baba-ẹgbẹ fun ẹgbẹ Afẹnifẹre nilu Accra dide, o sọ fun ọkẹ aimọye ọmọ ilẹ Naijiria to wa si ipade na wipe Ko si ohun meji ti wa fi pe ipade yi, bikọṣe wipe o tọ fun gbogbo a wa ọmọ ilẹ Naijiria nipataki, a wa ọmọ Yoruba ati ọmọ ilẹ ito ọmọ i lẹ to mbẹ nilẹ Chana loni ki A parapọ, ki a tẹrẹ ṣi se adura pataki fun iṣẹgun ẹgbẹ UPGA ti ọjọ Idibo wọn sile igbimọ asofin apa pọ Ijọba ilẹ Naijiria to ku si dẹdẹ.

Ọlọla Thompson fi nye ipade ọjọ na wipe kosi ohun ti a le ṣe bikose Adura nitoripe, kosi ibiti Ọlọrun kosi ati wipe, isẹgun ẹgbẹ UPGA lo le mu irọrun ati alafia wa fun awọn enia wa to mbẹ nilẹ Naijiria ati gbogbo awa ọmọ wọn to mbẹ loke-Ọkun.

ADURA UPGA TI GBA

Ki ẹniti o nṣọrọ o to ṣọrọ rẹ delẹ tan, Ọmọ Hausa Onisowo kan ti orukọ rẹ nje Mallam Shehu ti dide, o ṣe atako si gbolohun-Ọmọ Yoruba ati ọmọ Ibo nikan ti ẹniti o kọkọ sọra darukọ Alhaji Shehu sọ wipe:- Kotọ ki e ma darukọ ọmọ Yoruba ati ọmọ Ibo nikan si iru ọrọ banta banta to delẹ yi bikọṣe gbogbo ọmọ ilẹ Naijiria to mbe loke okun

Alhaji Shehu nṣọrọ rẹ na ni asọye wipe o tọ kia parapọ se Adura ṣugbọn on ri daju wipe Adura ẹgbẹ U.P.G.A. ti gba lati ọjọ ti edeaiyede ti de si arin ẹgbẹ Olomi (NPC) pẹlu ẹgbẹ Alakuko (NCNC) eyiti o mu ẹgbẹ Alakuko fi dapọ mọ ẹgbẹ Afẹnifere, ti awọn mejeji ti di ọmọ inu iya kanna, ti adape orukọ wọn di UPGA nilẹ Naijiria loni.

Nipari ọrọ rẹ Alhaji Shehu tun nsọ ni asoye lọjọ na wipe - Gbogbo awọn ji awọn jẹ ọmọ jẹ ọmọ ilẹ Hausa to mbẹ l'Oke okun lo nfẹ iṣẹgun U.P,G.A ati iṣẹgun

Ọ'ọla Ọbafẹmi Awolọwọ nitori pe, Awolọwọ ni Dọkita ti o le wo Amodi ilẹ yoruba ṣan.

IBOSI AWOLỌWỌ

Ki Alhaji Shehu to sọ bẹ delẹ tan, ibosi Awo! Awo!! Awo!!! gbojikan ilu Accra ni alaiko ṣẹku ẹnikan ninu ile ati ni gbangba ode, eyi ti o fi jẹ wipe, a pe laaigun ni awọn ọmọ ilẹ Ghana npe Awo! Awo!! Awo!!! ni alaikọmọ Awolọ wọ na ri rara.

£600 NI OWO SAARA

Lẹhin ti awọn enia jankan-jankan ninu ọmọ Yoruba Ọmọ ilẹ Ibo ati awọn gbajumọ Hausa t'o mbẹ ninu ipade ọjọ na sọrọ tan ni gbogbo wọn fi ohun sọkan fun ibẹrẹ Adura pataki fun iṣẹgun ẹgbẹ UPGA Owo ti nwọn dajọ larin ipade ọsẹ na fun eto bi nwọn yio bẹrẹ tise Adura na jẹ egbẹta pọun, silẹ mẹjọ ati kọbọ mẹfa (£600 8s 6d) Lẹhin idawọ ni ohun jijẹ ati ohun mimu bẹrẹ si kẹlu ara wọn, ti orin ati ijo bẹrẹ Nwọn ṣe asun ọjọ na di owurọ ọjọ keji ki nwọn o to tuka lọ si ibugbe wọn.

Orukọ diẹ ninu ilu ti isọri ẹgbẹ kọọkan ti wa si bi ipade na ni awọn ilu bi:- Swedro; Kede; Akwatia; Koforidua; Pram Kese; Asamanke e; Akim - Ọda; Cape-Coast; Elmina; Sekondi; Takoradi; Tarkwa; Foso; Kumasi; Ayinnam; Kadjebi; Kpedze; Hohoe; Aboasi; Dunkwa; Bibiani: Sultpond: Iyankroom ati ọpọlọpọ ilu miran nilẹ Thana ti a ye ko gba lati darukọ wọn sihia tan.

Bi ipade na ti dun to, apoti ọti Bia meji ati igo ọti Shinabu kan ni nwọn mu ni amuku silẹ, eyiti o jẹ ere iṣẹ awọn Sabarumọ to wa ba wọn palẹ Aga ti wọn fi joko mọ lọ sile Alaga.


BERE IGBOGI PATAKI YI TI NWỌN NPE NI:-

## "Apias Reducing Dragees"

Jẹ ojulowo egbegi ti awọn Jamani ṣẹṣẹ ṣe iwadi rẹ fun awọn ti o ba sanra tabi ti o ba TOBI ju latima mu ki nwọn le fọn tabi ki wọn fọnku lai si wipe nwọn ma ka ewọ onjẹ ti nwọn yio maa jẹ rara, bẹsi ni ko lewu ni lilo fun enia yala ọkunrin tabi Obinrin rara.

Ki enia ṣanra, ghorin, tabi kio tobi pupọju ki nṣe ohun ti o dara o si lewu pẹlu ọpọlọpọ amodi ni o nko Aya lilu kiki tabi jija nigbakugba aikole mi kanlẹ daradara, ara wiwo tabi wiwuwo; Eemi mimi họ họ ati oriṣiriṣi amodi omiran pẹlu

Ṣa dan Igo rẹ kan wo, Iwọ na yio ri ayipada ati Alafia ti yio de si ọ. Bere ni Ṣọbu awọn Olori Elegbogi Jamani ni Igboro Ilu Eko

Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos, Nigeria.



Printed And Published by Modupẹ Printing Press, 16. Bamgboṣe Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Cambell Street Lagos (19/12/64)